**EPISODE 15**

**Characters**
Tayo
Lami
Bello
Abokede
Iyabo
Umaru

---

**SCENE 1**
**Ibadan, Lami's House, Morning.**

1. **SFX:** **(OFF MIC) NEIGHBOURHOOD SOUNDS; (ON MIC) SOUND OF BABY CRYING AND WATER SPLASHING**

2. **LAMI:** **(LOVINGLY)** Omo Oba, omo mi atata maa sunkun mo..Iwo naa mo bi oju re ti hun jo. ..

3. **TAYO:** **(HAPPY)** Ahhh, Lami.Omo daadaa ni.

4. **LAMI:** Tayo, o wa mbe yen ni? Igba wo lo wole ti mi o mo?

5. **TAYO:** Bee ni o le mogba ti mo wole, mo kanlekun sugbon Omo to n korin fun ko le je ko gbo.

6. **LAMI:** Kaabo, kaabo. Ma binu pe ibenyen doti die. Kororun lati toju awon Omo keekeke meji. Eyi egbon yii Ijangbon re tie po..

7. **TAYO:** **(LAUGHS)** Lami, ma yo ara re lenu. Ibi yii naa da. Mo baa won Omo re ra nnkan wa ni.

8. **SFX:** **SOUND OF NYLON (*PLASTIC*) BAG BEING OPENED**

9. **LAMI:** **(SURPRISED)** Eleyii maa daa gan ni o

10. **TAYO:** **(DISMISSIVE)** Ki wa lo tii ri?

**11. LAMI:** **O seun o ku anawo si**.

**12. TAYO:** Ko si wahala, mo gbo pe Mama re ti de, se mo lei won?

**13. LAMI:** Ose to lo ni won de, won wa bami toju omo ni. Won lo soja wono nip e de mo.

**14. TAYO:** Olohun ma ba o se ti won wa o.kii se nnkan to rorun ki i o ma si oluranlowo fun abiamo, paapaa omo kekere bi re. Aunty Iyabo ni ko bi ki won salaye lati igba ti Abokede ti lo, ko rorun lati tun ile se mo bii ti tele

**15. LAMI:** Ooto ni o. Iya mi lo n bami sebe, foso ati ile titunse. Wahala n ii ba fee pa oluware bi ko ba si awon.

**16. TAYO:** Maa wa ki won nigba ti won ba pada de.
**(OFF HANDEDLY)** Umaru nko?

**17. LAMI:** **(GUARDED)** O wa, ise po lowow re gan bayii.

**18. TAYO:** Bami toju re daadaa o, mo feran re gan ni o.

**19. LAMI:** **(COLDLY)** Mo mo.

**20. TAYO:** Emi ati Umaru ore timotimo ni wa. Koda ipo to way ii gege bi Iyawo re emi ni mi o ba wa mbe.

**21. LAMI:** **(STILL COLD)** Ko fi nnkankan pamo fun mi nipa nnkan to ti wa laarin yin ri

**22. TAYO:** Se pe o mon pe a gba lero pe a fe fera.

**23. LAMI:** **(ANNOYED)** Mi o mo nipa iyen, Nibo lo n boro lo na, Tayo?

**24. TAYO:** Fokan re bale, se bi mo kan n ba o sere ni. A kan n soro gege bi Obinrin s'obinrin ni.

**25. LAMI:** O se Obinrin s'obinrin, ko se Obinrin s'obinrin. Iwo lo mo, sugbon je ki nso fun o, bi o ba ro pe o le fe Oko mi, lo muieyn kuro lokan tori ko le seese. Umaru feran mi ko si fimi sile ko wa fe e lailai.

**Ri sile**

**26. TAYO:** **(ANNOYED)** Ta lo fe gba Oko re? Bo ba se pe mo fe fee ni , i ba ti femi ko to mo o.

**27. LAMI:** **(MOCKING) Ki wa lo wa, wa sibi fun to wa n so isokuso nigba to mo pe o ni nnkan lokan.**

**28. TAYO:** Je ki n so fun e, n o gbiyanju ati fe tori mo mo nnkan to daa fun mi ni.

**29. LAMI:** **(LAUGHS)** Tayo, alawada ma ni o o. ko buru je ki n gba o nimonran kan. O kii S'omode mo o, lo wa Oko tie fe. Ko fi awon Oko oloko to ntelekiri sile.

**30. TAYO:** **(HISSES)** Ebi re ko.

**31. LAMI:** Dakun mu ebun iro re to ra wa dani o. Ko sohun ti a fe fi se o.

**32. MUSIC:** **<u>BRIDGE UP AND FADE</u>**

**<u>SCENE 2</u>**
**Ilorin, The Market, Afternoon.**

**33. SFX:** **<u>MARKET SOUNDS, PEOPLE SELLING THINGS, SOUND OF CAR AND MOTORCYCLE HORNS.</u>**

**34. ABOKEDE:** E kaaro sir, kin le fe?

**35. BELLO:** **(PLEASANTLY)** Nje o ranti mi?

**36. ABOKEDE:** **(EMBARASSED)** Mr. Bello.

**37. BELLO:** **(LAUGHS)** Good memory, bawo ni nnkan Abokede

**38. ABOKEDE:** **(EMBARASSED)** Ahh, se pe e ranti oruko mi ?

**39. BELLO:** Iwo nikan ko ni kii gbagbe nnkan.

**40. ABOKEDE:** **(LAUGHS)** E o puro

**41. BELLO:** Kilode to kan lo beyen lojo yen? Nnkan to se sasa eniyan lo le se iru re. Mo tun wa fe fi emi imoore han, o tun ko lati gbaa.

**42. ABOKEDE:** **(UNCOMFORTABLE)** Mo so pe, ko ye ke fun mi ni ebun fun nnkan ti mo se. Mo mo tori pe mo mo pe nnkan to to lati se ni. Kii se tori ebun.

**43. BELLO:** Sibe naa oore nla gbaa lose fun mi. Awon nnkan ti mo ra bo fun o lati trip mi niyii. O si gbodo gbaa.

**44. ABOKEDE:** **(INCREDULOUS)** Mo gbodo gba?

**45. BELLO:** Well, mi o so pe dandan o gbodo gbaa, sugbon mi omo nnkan ti mo fe fi bag obinrin ati perfume se. To ba se pe Okunrin ni o bayii ni, n oba so pe ki n lo lo won fun ara mi.

**46. ABOKEDE:** **(LAUGHS)** Eleyi ti poju, e ma binu n ole gbaa.

**47. BELLO:** Boya ki n si lo so gbogbo re nu

**48. ABOKEDE:** **(SHOCKED)** Kilode, won daa gan ni, mo si mo pe won maa won pelu. Ma soo nu o. O le ta won.

**49. BELLO:** Iwo ni mo raa fun. Joo gba

**50. ABOKEDE:** O daa mo ti gbo maa gbaa. Nnkan to nsemi ni peno mo nnkan ti maa fi bag ati perfume to daa bayii se.

**51. BELLO:** Ki lo n so, se o kii jade ni?

**52. ABOKEDE:** Nibo ni mo ni ti maa loo?

**53. BELLO:** Abokede, o yato si gbogbo awon Obinrin ti mo ti n pade tele

**54. ABOKEDE:** **(SURPRISED)** Itumo?

55. **BELLO:** Akoko ni pe o ka nnkan afeaye kun nnkankan. Ekeji nip e bi o ba se awon Omo mii to wa nipo to wa yii ni, ki n ma ti soro yo ti gba gifts yii lowo mi. Sugbon iwo tipatipa ni mo fit ii mo o lorun. Ko to gbaa lowo mi.

56. **ABOKEDE:** **(LAUGHS)** Boya e pade awon omo gidi ti won ko ti won si gbko ni.

57. **BELLO:** **(AMUSED)** O le je bee. Anyway, n o r ope a raye se introduction lojo akoko ti a pade.Gege bi o ti mo, Bello Animasahun ni oruko mi. Bakan naa ni o si mo ibi ti mo n gbe. Iwo nko? Se adugbo yii ni o ngbe ni ?

58. **MUSIC:** **<u>BRIDGE UP AND FADE</u>**

**<u>SCENE 3</u>**

**Ibadan, Lukman's Compound, Afternoon**

59. **SFX:** **<u>NEIGHBOURHOOD SOUNDS. (OFF MIC) SOUNDS OF TRAFFIC IN THE DISTANCE.</u>**

60. **IYABO:** Tayo o ti de,...**(CONCERNED)** Ki lo se o to waro kale bayii. Se ko saa si laburu.

61. **TAYO:** **(UPSET)** Aunty Iyabo e fimi sile jare. Sebi omo iranu to wa nisale ti won n pe ni Lami yen ni

62. **IYABO:** **(HISSES)** Oniranu

63. **TAYO:** **(UPSET)** Aunty mi, nnkan ti mo lo se ni ki n fun Omo re ni ebun ti mo bar a o. N o mo pe mo n lo kabuki ni.

64. **IYABO:** Iwo lo jebi, ki lo lo sibe fun. Omo oko yen ma ti bere si huye. Se mo so fun e pe o yaju semi naa.

65. **TAYO:** **(SHOCKED)** Lailai, nigba ti o jose.

66. **IYABO:** . Bi emi naa ti ro ni pe ko ye ko je bee. o je bee o. Mo lo ki kuewu Omo ni o. Ko tie je ki n wole to fi bere sibu mi. N se oo lo lemi bi en laja **(ANGRY)** Ni ile mi

67. **TAYO:** Eyin naa e mo nnkan, abi abisinwin n yoo lenu ni.

68. **IYABO:** Rara o, nnkan to nbe ninu re loti paa ba o. O ro pe Oko awon loun wa ni. Nigba ti mo ba si lee yo mo pe inu ile je abe oode

69. **TAYO:** Nnkan to ma n so ni pe mo fe gba oko oun.

70. **IYABO:** Ma daa lohun, oun naa ti n gapa ni. O ti n huye, gege ni maa gee gbogbo iye re danu ti mo ba raye tie.

71. **TAYO:** Ti kii ba se pe Umaru o gbon, ki lo lo fe iru eleyii fun.

72. **IYABO:** Aanu Umaru semi gan ni, enu re o ka Iyawo re.

73. **TAYO:** O yami lenu o.

74. **IYABO:** Sugbon enu re ti o ka Iyawo re yii ti sakoba fun un.

75. **TAYO:** Bi bawo o?

76. **IYABO:** N o so fun Lukman, omo oko yen o le maa bawa gbe nihin mo. Ko lo ma gapa re nibomii.

77. **TAYO:** Bee ni o. O ye kaa ko o lekoo abi iru iwosi wo niyen.

78. **IYABO:** **Gba nnkan ti mo so Tayo, ikoko o ni gbomi ko tun gbeyin ninu ile pelu emi ati Lami. Enikan gbodo year fun enikeji. Mo si mo pe yo lo fun mi ni.**

79. **MUSIC:** **<u>BRIDGE UP AND FADE</u>**

<u>SCENE 4</u>
**Ibadan, Lami/Umaru's House, Evening.**

80. **SFX:** **<u>SOUND OF KEY IN LOCK AND DOOR OPENING AND CLOSING. SOUND OF DOOR BEING LOCKED. (OFF MIC) A DOOR IN THE HOUSE OPENS AND CLOSES</u>**

81. **LAMI:** **(OFF MIC)** Umaru se iwo niyen?
**(COMES ON MIC, HAPPY)** Haa kaabo Oko mi

82. **UMARU:** **(PLEASED)** O seun Ololufe mi, se daadaa ni mo bayin ?

83. **LAMI:** Daadaa la wa. Maa so nnka to sele fun o bo-ba-ya. Je ki n tete dana tan ka wa soro.

84. **UMARU:** O sin run didun o. Iwo ati Iya re,e ma je ki nsanro o.

85. **LAMI:** **(LAUGHS)** A ti e ti so pe o ru tele. Ma je ki won maa so pe a n lo o bi eru.

86. **UMARU:** **(LAUGHS)** Lailai, maa so fun won pe ko ri bee.
**(IN A MORE SERIOUS TONE)** Ehen, mo ri Iyabo nita nigba ti mo n wole bo. Mo kii sugbon ko dahun daadaa. Mo wa n wop e ki lo n sele, abi nnkan ti sele nigba ti mo lo sibi ise ni.

87. **LAMI:** Obinrin to buru yen ati Tayo aburo re ni won fe mu aye su oluware. Emi o mo bi awon agbalagba a se maa se bi omo kekere.

88. **UMARU:** **(GENTLE SCOLDING)** Laa-mi,iwo ati enu re to mu yii, sora re o. Iwo naa mo pe ko si nnkan ti Iyabo o le se o.

89. **LAMI:** Ooto lo so, sugbon n o le forijin Iyabo fun emi emi ati Omo mi to fi wewu.

90. **UMARU:** Joo, fi Iyabo sile. Omo mi nko? Se o gbe lo si ile iwosan lonii?

91. **LAMI:** Bee ni a lo. Nurse ni ara re le daadaa.

92. **UMARU:** Adupe lowo Allah.

93. **SFX:** **<u>SILENCE (REALLY EMPHASIZED SO IT'S SLIGHTLY AWKWARD AND UNCOMFORTABLE)</u>**

94. **UMARU:** **(SLIGHTLY CONCERNED)** Lami, se ko si?

95. **LAMI:** **(EMBARASSED)** Ko si, kilode to fi so bee?

96. **UMARU:** Bo ti duro ati oju to fi wo mi o ri bakan. O johun pe o fe soro kan. Abi nnkan kan sele ni?

97. **LAMI:** **(SHY AND EMBARASSED)** Looto ni oro wa, sugbon n o mo bi mi o ba ti so fun o.

98. **UMARU:** Kin ni?

99. **LAMI:** Umaru, joo ma binu o.

100. **UMARU:** **(HALF-TEASING)** Kini, ki lo se?

101. **LAMI:** **(NERVOUS LAUGH)** Umaru fara bale.

102. **UMARU:** O daa mo n gbo o, ki lo fe?.

103. **LAMI:** **(SHYLY)** Nigba ti mo lo si ile iwosan loni, won so fun wa nipa ifeto somo bibi.

104. **UMARU:** Ki lo n je bee?

105. **LAMI:** Nurse so fun Mummu mi pe a gbodo sinmi ka to bi Omo mii.

106. **UMARU:** Looto.

107. **LAMI:** Bee ni. Won ni oyun ninu kii see eru kekere, pe o ye ki awa Iyalomo maa sinmi daadaa ka to loyun le Omo wa.

108. **UMARU:** **Oro gidi ni won so o.**

109. **LAMI:** Won tun so pe o ma je ki nnkan rorun fun wa bi a ba le se ifeto somo bibi. Oma je ki alaafia Iya ati Omo o peye, bakan naa ni ma lokun ati agbara lati le toju ara mi ati Omo. Bakan naa ni a o le ni fowo pamo daadaa fun itoju awon Omo ta ti bi.

**110. UMARU:** O daa, bawo la ti wa fe see.

**111. SFX:** **(SHUFFLES SOME PAPERS)** **<u>SFX: SOUND OF PAPER SHUFFLING</u>**.

**112. LAMI**: Awon iwe pelebe pelebe ti won fun mi niyii. Won ni orisirisi ona lo wa taa fi le see. Nurse ni ti a ba n fe imoran ka yoju si oun tabi ile itaja oogun to ba ni ami Ajose *GET IT TOGETHER. O risirisi ona ni won so pe o wa ti toko tiyawo fi le dena oyun nini.*

**113. UMARU:** **(INTERESTED)** Pelu eleyii, a o ni se eyi ti Mummy so yen mo niyen.

**114. LAMI:** Ewo niyen?

**115. UMARU:** Won so pe kin ma sun mo o titi ti Omo fi ma ape odun kan. O dabi eni pe pelu ifeto somo bibi eyi ti o mu way ii, ao ni ma gbadun ara wa lo ni?

**116. LAMI:** **(LAUGHS SHYLY)** Se nnkan to n so niyen,Umaru?

**117. UMARU:** **(LAUGHS)** Rara o, sugbon Iroyin to mu way ii daa pupo. Emi naa ri wahala re ninu oyun to koja yii. Idi ti n o fi janpata niyen pe bi won ba ni ki n duro ma duro, ki ara re fi mokun daadaa ni. Ka to ma sese maa so ki eeyan toju awon Omo daadaa. Anfaani pupolo wa ninu keeyan feto si omo bibi. Igbeaye alaafia ni fun gbogbo wa.

**118. LAMI:** **(HAPPY) Inu mi dun pe o gba.**

**119. UMARU:** **(TEASING)** Pe ko ni fa ipalara fun Iyawo mi atata tie dun mo mi gan ni.

**120. LAMI:** **(GIGGLES SHYLY)** Umaru, o ti to, o si fe je koju maa timi.

**121. MUSIC:** **<u>BRIDGE UP AND FADE OUT.</u>**